Chief Secretary to the Govern't

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD

VOL. VI. No 2?8 SATURDAY, OCTOBER 27 1978 4d

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.


## White's Radical Gonkiller.

—:o:—

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra. to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

—:o:—

[ *Fun Atọsi laílai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa orişi arun mi wa, bi:—Jẹdi jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

N.B.—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, l o si nję ki o ti aye wu arun mi silę.


Adeniji

Akin Adesigbin


LOOK FOR
THE PORTRAIT
OF
Dr. Earl S. Sloan
SLOAN'S
N & B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Carton adopted 1916.
FASSETT & JOHNSON,
Road. London. E.C.
ST. LOUIS. TORONTO. CAN.
BOSTON
in United States of America
TO
STOP YOUR
ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers,
Wholesale Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd London,
England

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILE NI OWO GBIGBA RE.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

IJA IGBORO TABI NLA?

Irọkẹkẹ ija kan ti awọn ọdọmọkọnrin kan ja leti Ila Faji ni ọsan *Sunday* tokọja mu ẹnikẹni ti o gbọ irohin na takiji: a gbọ pe ija na ko lori ko ni idi bi ejo Oṣun, a si tun gbọ pe abẹ lilọ ko 'jinna si awọn gende ti nwọn nja na tobẹ ti o fi jẹ pe awọn ero igboro ni lati sare kitikiti ki nwọn ma ba fi ara gb'ele, tabi ki nwọn fi ikun iyan gb'ọgbẹ: fun akoko diẹ a sọ pe ko si ẹniti o le gba ibi ija yi nitori "sise na" ti awọn arijẹ-nija wọnyi "sena" eyi ti jẹ o, ẹnyin alaṣẹ ilu.

———————

## DUNIYAN—LABARI.

[ LATI ỌWỌ KEKERE-AWO. ]

### IGBIMỌ-AṢOFIN.

Ipade Igbimọ-Aṣofin *Legislative Council* mbẹ ni Ṣẹkiteriati ni ọjọ 24 oṣu to mbọ gẹgẹbi atẹhin wa, a tanma pe awọn aṣoju-ilu tuntun mẹta yio ti ma gbaradi lọwọlọwọ yi, afara ko si o mẹmba.

### OUIGBO O ṢE!

Oyinbo H. M-M. Moore, ti a mọ ni adele igbakeji Gomina, a gbọ wipe o ba ọkọ *Accra* ti o ṣi nihin lọjọ Jimọ to kọja lọ si ilu oyinbo, fun faji lẹhin eyi yi ni yio tun bẹrẹ iṣẹ titun ni ilu Kenya—Ọkọ a refo o.

### LỌYA KUṢIKA ROBERT.

Ọgbẹni Lọya Isaac Kuṣika Robert lọ si ọna Warri ni owurọ ọjọ Satide to kọja yi, a fi aniyan sin ẹ o.

### GBADAMOSI DABIRI!

A ki gbogbo ọmọ-oloku patapata pe nwọn ku ọfọ baba wọn Ọgbẹni Dabiri, ẹniti a gbọ wipe o jalaisisi ni ile rẹ ni Taiwo Street, lẹgbẹ ile Ọgbẹni Lọya Taylor ni owurọ ọjọ Satide, ijẹjọ, nwọn si sin oku rẹ lọsan ọjọ na.

### IYA ẸLẸHA.

Ni ọjọ ọsẹ ijeje ni a gbọ ti ọfọ Iya Ẹlẹha ti o mbẹ ni itosi Mọṣalaṣi Jimọ, nwọn si sin oku rẹ ni ọsan ọjọ ọsẹ na—a ki gbogbo ọmọ loku papa Lẹmọmu Ligali ati Abibi Nọla nwọn ku ọfọ Iya Ẹlẹha—Ọlọrun ki o f' ori ji i.

### (EKEJI)

Ọna ti aṣiri alabosi ngba tu 'ki iṣẹ ọna kan ọpọlọpọ ọna ni likiṣi fi ntu ko ni ogun Ọlọrun Ọba lo ntu, ni iwọn igbati enia ba ti mbẹ ninu ẹgbẹ kan ti ko ri aniyan ti o to wipe on le tete ri tabi bibẹkọ ti o ti fi ẹṣẹ mejeji rinlẹ gbayin ninu ẹgbẹ na ti o si tun pada wa nhu iwa aiṣedede pelu ohun ẹgbẹ, ti Ọlọrun ba ti tete tu aṣiri ṣẹ fun aiye ọran ti buṣe, eyi ki iṣe ohun ti a le ma fa lọ titi, ki a kuku si si-isi rẹ lo dara, dajudaju nigbati ẹnikan ko buwo ti nwọn ko nini rẹ, ọkan on papa ni lati ma jẹ kiri pe adede ni on mbẹ ninu ẹgbẹ na; eyi kuku sanju wipe nigbati ọran ba ti da bẹ iyẹn ni ki a boju to fun oluwarẹ lẹsẹkanna.

Bi o ba nlọ bẹ awọn ti kalarawọn nwọn kio yio moyi ohun ti nwọn ṣe tobẹ, igba ti a nba onimọnafiki ja ọdan, ki iṣe lẹṣẹkẹṣẹ ti nwọn ba ti da iwa-iwa wọn silẹ ni eyi ye, bi a ba nṣe bẹ, nwọn a ma pe ara wọn ni nkan danyan-danyan loju ara wọn.

Ọpọlọpọ oniwa-mọnafiki lo 'pọju ninu ẹgbẹ Dẹmọ ti nwọn ko fi ara wọn han, chun pataki ti o 'mu ẹlomiran hu iru iwa bayi ni a ti so mọ ọrọ lọsẹ tokọja, ṣugbọn bi awọn ẹniti nwọn ngba ibọdi si ko ba gbọn fere-fere bi ifi nkọ, ọpọlọpọ iru awọn ẹni baun ko ti mọratan latiba ẹgbẹ na jẹ ti Ọlọrun ko si gba a fun wọn, ju gbọgbọ rẹ, ẹ jẹki a ma fi iyedonu diẹ o nitori ọjọ mran.

Ki awọn ẹniti o duro ki nwọn duro wọn dede, ki awon ẹniti o si nṣe opa-eke opa-odo si mọ oju ara wọn, ki awọn ẹniti ara tutu ti fi iya wọn tọn ti ki nwọn ma tọnu ara wọn da udaju awọn ni oju yio ti pẹlu iwa aiṣedede wọn, ṣugbọn ẹsan mbẹ nigba o ṣe, a fi eyi ṣọrọ silẹ fun igbamiran.

## ALAMỌRI ỌRO LỌYA ZIZER NIPA TI ẸJỌ ELEKO.

Ni Kotu ganran ti *Nigeria* niwaju Ọlọla M. L. Tew Adajọ.

*Motion* Lọya J. C. Zizer mu ẹjẹ yi wa siwaju Adajọ M. L. Tew fun gbigbọ ni arọ *Monday* ọsẹ yi.

O de Kotu ni iwọn agogo mẹsan ku iṣẹju mẹdogun, pẹlu okete iwe otin to di wa, nwọn si fẹ bẹrẹ si ẹjọ ṣe.

Ọlọla Eric. O. Moore de Kotu ni agogo mẹsan ku iṣẹju marun.

Lẹhinna ni Ọgbẹni Howard Agbẹjọro Ọba de, Kotu kun biba ẹp l pọ awọn Lọya lo wa si bẹ, Awọn Onifila-funfun wa lọpọlọpọ ati *Chief* Oluwa, ati awọn Ẹbi Eshugbayi. Kotu si kun fun ọpọlọpọ enia lati wa gbọ nkan ti Ọgbẹni Zizer ma sọ, lẹhin eyi ni Adajọ joko ti Akọwe si pe Ẹjọ na.

Agbẹjọro Ọba sọ pe yio ṣoro lati ma ba ẹjọ na lọ nisisiyi. A fi ti a ba mọ awọn Lọya ti yio ṣe ẹjọ na.

Nipa aṣẹ Ọba *King* ati imọran ti Kotu Pirifi Kansulu gba Ọba.

A da ẹjọ Eshugbayi pada si ọdọ iwọ Adajọ fun yiyẹwo si i.

Nigbati emi Howard si tun pada bọ lẹhin isimi ti mo ti gba, ni a ba ti tun fun si ẹjọ na, lati ijẹwa, mo mọ pe Ọgbẹni Moore ati Robert ni wẹn wa fun ẹjọ yi. Ati pe Ọgbẹni Robert ti ṣe iwe ibura diẹ silẹ.

Ni ọsẹ tokọja ni Ọgbẹni Zizer ri mi o si sọ fun mi pe Eleko ti fun on laṣẹ lati ma ba ẹjọ on lọ.

Ni *Thursday* ọjọ kejidinlogun oṣu yi, (18th) iwe kan jade ninu *Lagos Daily News* pe Ọgbẹni Zizer lọ si Ọyọ, (lati lọ gba aṣẹ lọdọ Eshugbayi) (Agbẹjọro Ọba si yọ iwe *Lagos Daily News* na jade o si ka ilameji nibẹ) Ọgbẹni Zizer emi ko fẹ ki Kotu ka gbogbo nkan ti nwọn fi si nu iwe irohin si otitọ, gugbọn ero mi nipe ọrọ yi jẹ ọrọ tonipọn nitoripe a ko mo ibiti a wa.

Mo ri Ọgbẹni Moore, o wi fun mi pe awọn ti wọn fun on laṣẹ nipa ẹjọ na ko ti pa aṣẹ na loku u. Bi nkan tiri bayi ẹjọna ko ni le ṣeṣe a fi bi a ba mọ ibiti a wa.

Emi fo sọ pe ki Ọgbẹni Moore wa si Kotu larọ yi. O wa nibi nisisiyi, yio si so ti ẹnu rẹ.

Ọgbẹni Moore dide o ni niwọn oṣu diẹ sẹhin on ati Layọ Robert ni a gba fun ẹjọ yi ati nigbati aṣẹ kẹhin si de, a fi si Kotu a si fun mi ni diẹ ninu awọn iwe nipa ẹjọ na. O ni ẹnu si ya on, on si takiji nigbati Ọgbẹni Zizer sọ pe Eleko fun on laṣẹ lati ma ba ẹjọ na lọ, o si ni on fẹ gba awọn iwe nipa ẹjọ na lọwọ on.

Ọgbẹni Moore si sọ pe, on wi fun Lọya Zizer pe ki ṣe Eṣugbayi lo fun on ni ọjẹ na bikoṣe awọn Iyekan rẹ ti nṣe oju rẹ.

O ni gẹgẹ bi pa, on kole ko awọn iwe na fun Zizer. Ọgbẹni Moore sọ fun Zizer pe on ki fi agbara gba ẹjọ ẹlẹjọ ti a ko fi lọ on, on ni on a kuku yọ ọwọ kuro ninu rẹ bi o ba di bẹ ni;

O ni ninu ẹjọ ti Eleko yi awọn ti wọn fun on laṣẹ koi ti gba lọwọ on.

Kaka bẹ nwọn tubọ-ki on lọkan ni pa ẹjọ na... O ni bi ti on ti ri ni yẹn.

Lẹhin eyi Ọgbẹni J. C Zizer dide o wa bẹrẹ si sọ bayi pe :—

O to ọsẹ mẹta nisisiyi ti Ọgbẹni W. A. Dawodu wa si ọdọ on. O si sọ pe Lawani ọmọ Eleko wa si ọdọ on, on si sọ fun on pe nwọn ntan Eleko jẹ ni.

Adajọ :—awọn wo ni wọn

Ọgbẹni Zizer :—awọn Ẹbi ati awọn alatilẹhin rẹ ni.

O ni nwon sọ fun awon pe lẹhin igbati Aṣẹ Ọba *King* ba ti de ti a si mu lọ si Kotu, Eleko yio wale. O ni a Aṣẹ Ọba *King* ti de, a o gbọ pa, a o gbọ mu, Eleko ko wale. O ni gẹgẹbi mo ti jẹ Lọya, on ki ndide si ọrọ na, ki nsi ṣe atunṣe mo si so fun un pe, emi kole ṣe ohun kankan lai ko jẹ pe mo gba aṣẹ, Ọgbẹni Dawodu si lọ, o si tun pada wa o si wa sọ fun mi pe on ti ri Lawani Akọbi Eleko ẹniti o gbọjẹgẹ pe ki nma ba ẹjọ na lọ, adunadura iye ti mo ma gba. Dawodu si fun mi ni *Cheque*, mo si lọ fi gbo owo ni *Bank*.

Mo wa sọ fun Dawodu pe yio ba mi lọ si ọdọ Eleko lọyọ lati ba mi ṣe ogbifọ fun un, nipa aṣẹ na ti Eleko ba gbọjẹgẹ lati fi ọwọ si, emi yio ma ba ẹjọ rẹ lọ. Ọgbẹni Dawodu jẹ ọhun a si jọlọ, nigbati a de Ọyọ ohun kan kini ti mo ko ṣe mo yọ iwe irohin *Daily News* eyi ti nwọn tẹ sinu rẹ pe Eleko ti gba ẹjọ rẹ lọwọ mi. nigbati a ṣe ogbifọ rẹ fun nṣe lo ke—tara mo bi Ọgbẹni Dawodu pe kini de Ọgbẹni Dawodo sọ pe Eleko sọ pe on ko mọ pe nwon ti gba ẹjọ na kuro lọwọ mi pe on ko paṣẹ fun ẹnikẹni lati gba ẹjọ na kuro lọwọ mi.

O ni gbogbo nkan wonyi su on su u, agara da on yẹyẹ ti a nfi on ṣe ni gbagbogbo mo gba dun ara mi nigbati mo nde ọja, a ti mi si ipo yi ni, bayi la si nda mi riboribo lati ọdun yi wa o sun mi lọwọ maṣe ẹjo mi nso emi ko gba lọwọ rẹ rara.

Ti awọn yekan mi ati awọn alafẹhinti mi ti nwọn ti ntan mi jẹ lati ọdun yi wa o su mi.

O wa wipe, on yio fi ọwọ si iwe na'a ka a fọ ogbifọ fun un, nkan to wa nibẹ si ye dada.

Nigbati o fẹ fi ọwọ si iwe na ikan ninu awọn ọmọ rẹ ọkunrin wa o si wi fun un pe, Baba ma ti

fi ọwọ si iwe na jẹki a lọ si Eko na, inubi Eleko o gba ọmọ na ninu o wipe lọ nibi lati ọjọ yi, nisisiyi li a fẹ pari ọrọ na, o wipe ki ma fi ọwo si i, lọ nbẹ iwọ yi ò wa fi ika gbongbbo fi ọwọ si iwe na.

Adajọ :—Tani kọ iwe na.

Ọgbẹni *Zizer* :—Mo kan ko ẹda apakan aṣẹ ti a fi fun mi ni lailai ni, lẹhin igbati o ti fi ọwọ si iwe aṣẹ yi emi pada wa si Eko. *Mo* sọ nipa aṣẹ mi fun Agbẹjọro Ọba, mo lọ si ọdọ Ọgbẹni Moore o sọ pe ẹnikẹni ko fun on laṣẹ nipa ẹjọ na o fi iwe kan han mi nipa ẹjọ na eyiti orukọ Mr Macaulay wa, Ọgbẹni Moore sọ pe ọpọlọpọ awọn iwe lo wa lọwọ on nipa ti ẹjọ na, o ni on ko iti yẹ wọn wo, o ko wọn jade o ni ṣugbọn mo le wo wọn ṣugbọn on ko le fi wọn fun mi nitoripe Ọgbẹni Robert lo ko wọn fun on, mo si sọ fun u pe gẹgẹ bi awon iwe na ti pọ emi yio ko wọn lọ si ibi iṣẹ mi lati yẹ wọn wo ati lati kọ ẹda rẹ silẹ, emi yio si da wọn pada ni ọjo kan na, mo ko wọn lọ, mo si da wọn silẹ, mo si da pada fun Ọgbẹni Moore.

Ni Thursday ti o kọja mo ri lẹta ti nwọn tẹ sinu *Daily News* ti nwọn ni Eleko lo kọ, mo wọ wọn, mo ri pe nwọn ki işe iwe lọna ofin, mo lọ si Post office mo lọ bere bi mo ni lẹta, mo si ri kan ti a ko si mi mo tu wo mo ri pe ko ba eyi ti o wa ninu *Daily News* mu, mo ri wipe eru wa nibikan, mo kọwe si awọn Ọlọpa inu ki wọn ba le wa idi rẹ.

Adajọ :—Eyiti o wi yẹn ko wa ra ọrọ, ṣebi tirẹ ti jẹ ni yẹn nipa ọrọ na.

Ọgbẹni *Zizer* :—Bẹni.

Adajọ :—Iwọ rope eru ni lẹta ti nwọn tẹ sinu *Daily News* tabi to wa ninu *Daily News*.

Ọgbẹni Zizer :—Bẹni.

Lẹhin ọrọ diẹ, Kotu paṣẹ pe ki nwọn ṣe iwe ibura miran eyiti Eleko yio bura si niwaju oyinbo onişẹ Ọba ni Ọyọ ki o si yan Lọya ti yio ma ba ẹjọ rẹ lọ. Ọgbẹni Zizer ni on rope, Kotu yio yẹ irufẹ aṣẹ bẹ wo bi otọ ni bi otọ kọ, o tun sọ pe o da on loju pe awon enia miran le lọ si Ọyọ lọdo Eleko lati lọ da ru ba, Adajọ kokọ ibi ara si eyi, ṣugbọn o ni ki Eleko ṣe iwe ibura miran o ni iyẹn ni yio yanju ọrọ, Adajọ wa bi Zizer lere pe ti Eleko ba yan, bi yio lo iwe ibura ti Robert ṣe.

Ọgbẹni *Zizer* :—Bẹni ngo lo.

Agbẹjọro-Ọba :—Emi ko rope o le lo wọn laikojẹ pe o gba aṣẹ Lọya keji.

Ọgbẹni Zizer :—Mo rope mo le lo wọn bi a ba fun mi ni aṣẹ ẹjọ na, kotu si dara duro nihin.

***Lagos Daily News,* 23-10-28.**


# *KERE O!*

## OYINBO KESSLER GBE TANA DANU, O GBE MI DE.

Irin-iṣẹ Gbẹna-gbẹna to dara ju ti nwọn ti nlo fun iwọn adọta ọdun sẹhin wa fun tita ni Ṣọbu ***Kessler.***







Ẹ ba mi lọ si Ṣabu na, ẹ o ri ti nyin yan nibẹ, ọpọku ọyọku ni owo rẹ, iba diẹ ni o wa. Aworan Irin-iṣẹ wọnyi ni a ya sinu iwe yi fun nyin yi. Lọgan lẹ o ri ra.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo **KESSLER** ni No. 7, Labinjo Lane, ni Eko.







Ẹnyin ara Eko,, ara Oke, ati ilu miran, gbangba dẹkun, kedere bẹwo, Ṣabu Kessler ti kuro ni mori nkan firi irohin ko to afojuba. Ẹ ma ṣe gbẹhin ki ẹ to ra ti nyin, ki ẹ ma ba joku Ologbo.

## IROHIN ỌBA AKARIGBO ỌLỌLA ATI ỌBA ỌLỌLA ALAPẸRU.

A dupẹ pe Ọba Akarigbo ọlọla ọlaju Ọba ni nitori onigbagbọ ni. Mo ro pe ọlọlanla Akarigbo ni o gba Ọlọla Ọba Alapẹru ni yanju ti Ọba Alapẹru fi di Ẹgbẹ o *Church* titi doni nitorina mo yọ lati sọ fun nyin pe Ọba Alapẹru koni orișa kan ti wọn nta Epo le ni ori rara gẹgẹ bi Emi tiro nitorina mo fi ọwọ ati itẹriba bẹ ọlọlanla Oba Akarigbo ki o jọwọ ba wa bẹ Awujalẹ ọlọlanla ki ẹnyin mejeji jọwọ tubọ ba wa gba Ọba Alapẹru ni iyanju ko sinu ni Church Ọlọrun ki gbogbo Igbimọ rẹ ma wa si Church ati pe papa afẹ ki gbogbo awọn ọmọ Ọba tio wa ni orilẹ Ijẹbu ma wa si Church lati mọ ohun ti otọ ati eyi tioyẹ. Ati papa atun fẹ da ẹgbẹ ọlọrọ rere silẹ larin gbogbo Ijẹbu ati ni arin gbogbo enia pẹlu : Anpe orukọ awọn ẹgbẹ yi ni *Words Club Department* ni ati ma șanu fun gbogbo otoși tabi alaini ẹni ti anfẹ ko jẹ. Baba Isalẹ fun ni ninu ẹgbẹ na ni yi Oba wa Agba Ọlọlanla Awujalẹ ati Ọlọlanla Akarigbo si ilẹ Rẹmọ ki Ọlọrun jọwọ fun gbogbo wa ni ẹmi gigun ati alafia Amin.

## IROHIN NIPASẸ ỌKỌ ẸGBA TO KUN AKUNJU.

Ni ọjọ 19/10/28 mo wa ni ori kereni tabi *Bridge* ti Eko, mo ri awọn Ẹgba kan ninu ọkọ tẹrẹtẹrẹ yẹn ti nwọn ko epo kun inu ọkọ wọn ati ekuro pẹlu. Ẹnikan ninu wọn ko ju inch kan abọ tabi inch meji lọ. O san die ninu ito Ogun titi de Oko Baba nitori eti ișa ni awọn yẹn je, oju ibu odo o sa ko jẹ bẹ tabi ko ri bẹ rara. Awọn ọlọkọ bẹ yẹn le mu ko ẹru wọn tabi ohun mi wọn sinu motọ ni Oko Baba, bibẹkọ ki nwọn ma din ẹru tabi ini wọn ku, ki wọn ma ni ọkọ won kun tobẹ mọ, a ko fẹ ki ẹmi ẹnikẹni ninu wa ko ri jamba tabi ewu kan, mo fi ọwọ ati itẹriba bẹ Ijọba Gẹsi ki nwọn ba wa fi așẹ si ọrọ yi ki Ọlọrun ma jẹ ki a ri buburu larin wa. Amin.

A mọ dajuda u pe ewu wa nilẹ, ewu si tun wa ni oju omi nitoto, șugbọn eyiti a fi oju ẹni ri o yẹ ki a sa fun iyẹn daradara, nitorina ki Edumare jẹki ẹniti a fẹran rẹ ko tẹ wa, nitori gbogbo aiye ni nhu iwa ẹșẹ.

## IROHIN IJẸBU RẸMỌ ODE ILE ATI ȘAGAMU.

Agbo pe obirin da ogiri ile lu ni ode Odepeju ni Ijẹbu Rẹmọ ni oru, ọrọ ti ko wọ kama ri yẹn.

1. Bẹni wọn so pe Sefu sọnu ni Șagamu ni yẹn ni nkan bi 1925 tabi 1926 ni yẹn titi doni ako gbọ pe wọn ri Sefu na titi di oni oya ni lẹnu pupọ. Bẹni dajudaju enia ni wọn n fi kọkọrọ Sefu yi le ni ọwọ bẹni moro pe enia kan ni wọn fi șọ Ibiti Sefu na gbe wa mọju, wọn ni lati ri si yẹn Ijọba Igesi nitorina a nfẹ Ọlọpa Inu nipa ọran Sefu oriși mẹta ọlọpa ni anfẹ ki o ba wa wadi ọran Sefu ti o sọnu ni Șagamu ki wọn jo ma wadi rẹ, Ọlọrun yio tu ona așiri ẹni ti o gbe Sefu na Amin. Nitori awọn agba wa nsọ wipe Ogbo Ijẹbu ki gbe si Rẹmọ owe ni o.

2. Bẹni wọn gbe *Bookseller* si ode ti wọn fa ni irun ori ti wọn si gbe owo *Book Shop* lọ ni yẹn ni Șagamu kan na oya ni lẹnu pupọ.

Bẹni owe awon agba wọn ni Ifa kikọ ni mu ni Imọ Ifa ọna șiși ni mu ni Imọ ọna ọna ti a ko ba rin ri iyẹn ni ișeni șibala șibolo iyẹn ni edi ifa lun Ọsanyin ni igbati olodumare ran șẹ pe ogun pe ki o wa ba on wo Aho yi nigbati ogun mura ọsanyin ni on yio ba lọ si ọdọ olodumare bi wọn kuku ti nde ọdọ olodumare oranșẹ wipe ki wọn lọ mu Aja fun ogun ni tori onje rẹ ni yẹn bi wọn ti kuku fun ni Aja na bẹni ọsanyin ki ada mọlẹ o ni on ma bẹ Aja, nwọn kọ pe ko ma bẹ oni dandan on a bẹ Aja fun ogun ni aifagun lọ titi ọsanyin ni ko on bẹ Aja o fi ada șa ara rẹ ni ẹsẹ, ẹjẹ si bẹrẹ si șe to bẹgẹ ọsanyin șubulẹ nigbati eyi gbe nwọn gbe ọsanyin lọ si ile rẹ ni gbana ni olodumare fi ewe han wọn ti wọn lọ șe si ẹsẹ ọsanyin titi ẹjẹ fi da ati titi ẹsẹ fi jina. Ni ati ọjọ ni pe ama șe ewe ọsanyin nigbati oșe odi pe ama șe ọsanyin ni ati ọjọ ni ọsanyin ti gba oruko tio di olola nla ni yẹn ki Olorun jọwọ ti ilẹkun buburu fun gbogbo wa o. Ki Ọlọrun jọwọ și ilẹkun rere fun gbogbo wa o. Amin.

Emi ni tiyin nitotọ,<br>
J. A. O. SHOMADE.

---

98, Docemo Street,<br>
Ebute Ero,<br>
Lagos, Nigeria,<br>
October 22, 1928.

The Editor "Eko Akete"<br>
24, Williams Street,<br>
Lagos.

Dear Sir,

I observed in your issue for the 13th instant, page 7, in Olusakin's Column reporting the Divorce Suit against Barrister "Obafemi versus Obafemi," that I am referred to as "a popular jester and comedian;" which is not in any way a compliment; and as such, I take objection to that.

I here state for your immediate correction that I am not a jester and comedion; and that I had since 1925 established and registered as a Commission Agent here and elsewhere carrying on that line of business.

Yours faithfully,<br>
W. MENDS-COLE.

## "AWỌN ORORI NI WESTMINISTER ABBEY"

NIPA JOSEPH ADDISON

Nigbati mo wo orori awọn ẹni nla, ilara kan ko ku ninu mi.

Nigbati mo ka awọn ọro aro ti a kọ nipa awọn arẹwa, ifẹkufẹ gbogbo lọ lọkan mi.

Nigbati mo ṣe alabapade ẹdun awọn obi lori orori, anu gba ọkan mi kan. Nigbati mo ri orori awọn obi papa, mo ro ti yẹyẹ a nkẹdun fun awọn ti awa ma ko ni pẹ ki a to tẹle.

Nigbati mo ri awọn Ọba dubulẹ ti awọn ti o rọ wọn loye.

Nigbati mo ro ti awọn ọlọgbọn ti ntakọngbọn si ara wọn, bi a ti to wọn fẹgbẹ kan ẹgbẹ.

Tabi awọn Ojiṣẹ Ọlọrun, awọn ti o fi ija ati iyan jija da aiye ru.

Pẹlu ibanujẹ ati iyanu mo ro ti aitotọn ija ati iyan jija awa ẹda.

Nigbati mo ka awọn oriṣiriṣi ọdun, ti a kọ sara orori—ti awọn ti o ku lana, ati ti awọn ti o ti ku ni ẹgbẹta ọdun ọhun.

Mo ro ti ọjọ nla ni, nigbati gbogbo wa gba yio d'ẹgba, ti a o si jumọ fi ara han.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

---

### A CORRECTION.

In our issue of the 20th instant, under "Olusakin's Column" Mr. W. Mends-Cole was referred to as "a popular jester and comedian" the former term viz—"jester" being taken objection to by Mr. Cole: our Correspondent means no harm by this as a matter of fact, Mr. Cole's cheerful spirit has often helped to drive away the "blues" from many an audience as a gifted comedian. We regret the insertion of the term and unreservedly withdraw it.

It gives us pleasure to say that Mr. Cole has been registered Commission Agent since 1905 until now.

ED. E.A.

# NOTICE.

IN THE MATTER OF THE ESTATE OF

## AKINWUNMI AJOSE-ADEOGUN (DECEASED).

*Pursuant to the Statute 22nd and 23rd Victoria Chapter 35, intituled "An Act to further amend the Law of Property and to relieve Trustees."*

Notice is hereby given that all creditors or other persons having claims or demands upon or against the estate of Akinwunmi Ajose-Adeogun late of 25, Agbo o Street, Idoluwo, Lagos, Nigeria, who died on the 9th day of July, 1919, intestate, and Letters of Administration of whose personal property were on the 9th day of August, 1928, granted by the Supreme Court of Nigeria to Akinola Ajose-Adeogun of 9, Ajose Court, Lagos aforesaid, are hereby required to send particulars of their debts, claims and demands in writing to me the undersigned, on or about the 30th day of November, 1928, after which day the Administrator will proceed to pay and distribute the assets of the said estate among the parties entitled thereto, having regard only to the claims of which he shall then have had notice and that he will not be liable for the assets or any part thereof, so distributed to any person or persons of whose debt, claim and demand he shall not then have had notice.

And all persons indebted to the said estate or holding any effects of the said deceased are hereby required to make immediate settlement or deliver the same to me.

Dated at Lagos this 15th day of October, 1228.

AKINOLA AJOSE-ADEOGUN,
*Administrator.*

---


JUST ARRIVED.

**WASU**

journal of the West African Students' Union of Great Britain.

1/- per copy.

Obtainable at the office of:—

"TIKA-TORE" PRESS,
Broad Street, Lagos.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, OCTOBER 27, 1928.

## KINI L'ĘJĘ L'ĘJĘ—L'ĘJĘ

## OWO L'ĘJĘ L'ĘJĘ—L'ĘJĘ.

Ęda wo ni ko mọ pe ęję ni ęmi enia ati ti ęranko gęgębi oje-igi ti nmu awọn igi inu igbę dagba bęni ęję nmu enia ati ęranko dagba bi ęję ti ri fun enia, a le sọpe bę si ni owo ri pęlu.

Onişabu ti o şi Şabu rę fun ọja tita kilo nwą—owo.

Obinrin ti o ko ọja tita rę sori ipatę, kilo nwa—owo.

Alaru ti o nkakiri eti ebute laii ru ęru kilo nwa—Owo.

Oşişę ti o wa lo'run lojojumọ, kilo nwa—Owo.

Adajọ, Agbęjọro Ọba, Aşọde, Akọwe ati awọn onişę bawọnni, kini nwọn nwa—Owo.

Bęni: Owo ję ęję fun gbogbo ęnikęni ti o mbę lode aiye, t'ọmọde ti'agba: şugbọn a le sọpe ęję owo yi nşan tara lara olukuluku ni ode oni bi i? Ogọrọ enia ni yio jęri si evi pe "Igida" niti ode isisiyi nipa okuta tabi aita ọja nigbati Şabu kan ti ọja ti o mbę ninu rę to nkan bi ọlọgọrun pọun npa şile męfa ni ọjọ męta lati *Monday* di *Wednesday*, ę ko şai ri pe nkan nkan nigbana. Tani ko ke tan ni akoko yi fun aita ọja ati işę ti ko si lode? Onişowo nke, oşişę nke, Loya nke anisę aşegita nke. kilo tun ku. Inawo orişirişi ni o yọ lọtun losi bę gbogbo nkan wọnyi, owo ni nwọn nję, nwọn ki ję igbadọ: ęlomiran ko mọ ọna ti on le gba fun gbogbo orişirişi bukata wọnyi ta lo le sọ ogunlọgọ enia ti nwọn ti nşowo ri şugbon ti nwọn ti "Ko gba si le 'lo ni?" Kilo mu eyi wa bikoşe ęję (Owo) ti ko tun şan tara mọ biti igba atijọ fun awọn ęni ti a nwi yi hihahilo to wa fun awọn ęlomiran to mu ki o pa oluwarę: gbogbo nkan le koko bi oju ęja tobę ti o fi ję pe ironu mọ ę lọpọlọpọ fun irufę awọn ęni bayi, ogo ni awọn miran fi nlọ ya owo ele ti nwọn si nsan nkan bi şile męta męta tabi ju bę lọ lori pọun kọkan ti nwọn ya: ani ogo ni alaya meji męta nfi wa ọna lati le lọ ninu awọn aya wọnyi; ęlomiran tilę fęrę le wa ni abarapa eyi ni ni lalai fę ni obinrin kọkan mọ nitori ati ję ati mu rę: nigbati ko ba si loju kini o ma kan s'aiya o? Gbogbo enia kọ lodi oku apapandodo si iduro nitori ęję owo ti ko tun şan lara oluwarę mo: ęlomiran ko tilę tun mọ işę ti a muşe mọ lati le ma ri okele bu lojojumọ, ęlomiran ko si le fęrę le ma ke pe kini on tilę wa şe ninu aiye gidi, awọn ti ara ko rọ lode oni nitori aisi owo aisi owo firi awọn ęniti a le wipe ara rọ lọ bi igbati ę gba firi okan. Eko isisiyi Eko ọdaju ni, Eko tęmbęlękun ni, Eko "Ę mu re" Eko "jaginni o dun mo mi" ko dabi Eko atijọ, Eko ti o tutu bi ọsun ko si ęnikęni ti o le mọ igbati nkan tun ma lọ bi igba atijọ bikoşe Allah.

Ode oni su ęnikęni fun ijakadi ęję (owo) ti olukuluku nba ja pe ki o le şe arọwọto on ni gasikia.

"Irun'mu l'owo"

---

## IPADE DĘMỌ.

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*.

Mo bęrę f'oji,

Awọn ęgbę "Democratic Party" şe ipade Gbogbo-gbo won ni ọjọ Satide ọjọ kęfa osu yi, ni ile Afari-ogun (Glover Memorial Hall) ni abę Alaga Ogbęni A. W. Shackleford ati awọn Ọjọye Eletu Odibo, Tijani Olawa, Olumegbọn, Ashogbon ati Oshodi pęlu awọn Ogbęni T. H. Jackson, Ọlọla T. Adebayo Doherty, Ogbęni Thompson, Omsvery John, Briamh Igbo, Kadiri Ijaoba, Lemomu Lawani Aguda, Ogbęni Alęşinlọyę Williams, ati awọn Lemomu Ratibi.

Ogbęni Alęşinlọyę sọrọ pupo o to iwọn ogun işęju fun ọrọ rę, lęhin ti Ogbęni Shackleford ti

kede si eti igbo ẹgbẹ wipe Alaga Ọlọla Moore ara rẹ ko ṣe were lati wa si ajọ-lọjọ na.

A ti sọ ọpọlọpọ irohin nipa awọn ẹniti o sọrọ ni ipade na ninu iwe ti ọsẹ tokọja, gẹgẹbi ipinnu nigbati labari po fun wa, a fi labari ọrọ Oloye Oluwa ati Ọlọla Lọya Doherty si oni.

OLOYE TIJANI OLUWA :—Mo ki gbogbo ẹgbẹ patapata lọkunrin, lobinrin, lọmode ati lagba, mo tọrọ adura ki Ọlọrun jẹki ẹmi gbogbo wa o gun, ki o si bo aṣiri wa, gẹgẹbi a ti nwa rere ilu yi, ki O jẹki a ri rere ilu wa na—Amin.

Ohun ti mo kọ fẹ bere lọwọ nyi ni wipe ibo ti a di yi fun ire apakan tabi fun ire gbogbo ilu?—ẹgbẹ :—fun ire gbogbo ilu ni.

Ẹ jẹki a dupẹ lọwọ Ọlorun, ki a si pada wa dupẹ lọdọ Ọgbẹni Shackleford nigba ti ko ni iye, nitori o jagun o si ṣe bi balogun ti nṣe fun wa, a ko lero rẹ si, nitorina, mo tun fẹ ki ẹ dupẹ fun un, ki gbogbo ẹgbe si dupẹ fun Ọgbẹni Thompson ati fun Ọgbẹni Alẹṣinlọyẹ na pẹlu, fun gẹgẹbi nwọn ti duro girigiri lọjọ na, ti nwọn o ye, ti nwọn o gbo, ti nwọn si ṣe bi ọkunrin ti ni lati ṣe, ki ẹ si tun dupẹ fun Ọgbẹni Leigh na pẹlu.

A dupẹ fun awọn ẹgbẹ "Young Nigerian" fun ileri wọn ti nwọn ṣe wipe ibiti ẹgbẹ Dẹmọ ba gbe nlọ nibẹ ni awọn na nlọ.

Nitotọ ọmọde ni wọn, ṣugbọn ẹyin lọ ndi akukọ, ki Ọlọrun jẹki nwon to agba, ki awọn Kiriyo ma ṣe "Thank God" ki awọn Musulumi si ma ṣe "Alihamdu Lilahi." Ni ọdun karun, ti a fẹ di'bo nihin fun Aṣoju mẹta ti Ijọba nfẹ ni Igbimọ-Aṣofin, ibo ti awa ti a di fun awọn Aṣoju mẹta ti a yan lo mu, nigbati o si tun di aseko ti ilu yio ni Aṣoju mẹta bakanna ni Igbimọ ti Munisiba ni ọdun 1926, awọn Aṣoju mẹta ti a dibo fun nihin lo tun mu, ibo ti a si tun di nihin lọdun yi, awọn mẹta ti a tun yan ni ibo wọn tun mu, a dupẹ lọdọ Ọlọrun.

Awọn Kiriyo ti nwọn ba lọ tọrọ iyawo lati gbe e, ki nwon to wọ inu ile ana, nwọn o duro ni ojude, nwọn a ma daṣa kan, nwọn a ma sọ wipe ẹ ku alẹ Ṣi, ẹ ku alẹ Ma, lẹhin eyi ti nwọn ba da wọn lohun tan, ti nwọn ba fẹ lọ si ile, nwọn a ni "Ẹjọ wa jare gbangba"—ẹjọ wa jare gbangba, ẹ jẹki a mu Ọpẹ na lọ si Ọdọ Ọlọrun, ti O da wa lare, nitori kini ; eyiti nwọn nro ọdan, ti Ọlọrun ọdan, ṣugbọn ti Ọlọrun Ọba do ṣe, nitorina fun eyiti Ọlọrun ṣe fun wa, ki gbogbo Ọmọ-ẹgbẹ ati ara ode mọ wipe, Ọlọrun yio tun ti olukuluku ṣe.

A bẹ nyin pupọ nipa apara pe ki ẹnikẹni maṣe da apara ki apara kan lode, oni-bantẹ clododo lo nwa, oni-tẹkọ ati alaran ti nwon ba pade ana wọn ni ọja, oni tẹkọ a lọ ba alaran pe ija on ya, ṣugbọn alaran yio ma pa suru fun oni-tẹkọpẹ maṣe ba ẹnikẹni di apara, "A njuwọn ko ṣe wi lẹjọ ija lara ko tan bọrọ" ibiti a nlọ o jinna pupọ, ibo ti a di yi ki a to di nwọn gbọ ni ilu Oyinbo.

Nkan ti o ku ki on fi ran wa leti, ni wipe ipade ti a ṣe nihin loni, pẹlu owo ni, o ba yẹ ki a si ma gbọ wipe bi a ti nṣe to yi, ati bi a ti po to yi, sibẹ-sibẹ a ko ni owo lọwọ to, nje ko ti wa loju, a bẹ Ọlorun ki o ma ṣe a ilẹhin fun wa, ki o si dawọ iku ojiji wọnyi duro fun wa.

Awọn mẹta ti a yan yi, a yan wọn na, Agẹmọ ni on bimọ on na, ẹnyin ti a yan ẹ ko si nihin, ṣugbọn nwọn o ma sọ fun nyin nile, ti oni ko ma jọ ti ana, a yan Ọlọpa-inu ti nyin, ẹru ti a gbe le nyin lori, eru ti o wuwo pàpà ni, nigbakugba ti a ba nyan nyin, awọn enia yio ma sọ bi aseko olukuluku ti ri, ki igba ẹnyin mẹtẹta ti a ṣẹṣẹ yan yi dara fun wa o, ki ẹ lọwọ ki ẹ gba wa o.

LỌYA ADEBAYO DOHERTY :—Mo ki gbogbo nyin patapata lọkunrin ati lobinrin, lọmọde ati lagbalagba, ilu na yio dara fun wa, ede arawa ni mba ba nyin sọ, ki ẹ ba le mo mi ni ọmọ Eko daradara, ṣugbọn Oyinbo kan ti o mbẹ nihin ati Alaga ko jẹ. Ipade ti a wa ṣe nihin loni ipade ti ayọ ati ti iṣẹgun ni, ogun wo? Tabi tani a jagun na fun? Nitori emi ni.

Inu mi dun lati ri wipe ẹ ka mi kun, ẹ ko si fi oju tinrin mi, lati igba ti a ti bẹrẹ ipalẹmọ, ni ogun na ti le koko bi oju ẹja, emi si ni ọran mbawi.

Lojọ ti iwe mi ti jade wipe ti ẹ ba fẹ yan enia, ki ẹ yan mi, lati ọjọ na, ni ogun ti de ogun yi le titi o tilẹ di tẹmbẹlẹkun gbanran, ẹniti o jẹ wipe o nta mi laiya ni ajọ Komiti ti Ọgbẹni Bagan Benjamin, ọkunrin yi Ẹni-ọwọ ni lọdọ mi, nwọn jumọ yan wa si Igbimọ (Munisiba) ni, mo si mọ wipe o nṣiṣẹ daradara, ṣugbọn o wa gbagbe wipe gbogbo iṣẹ ti a nṣe ko ni a ploṣo ti, titi di oni a-ri-yọ ni fun emi pẹlu rẹ.

Lẹhin ti Komiti yan mi ṣikẹta, ni nwon ti bẹrẹ si bu mi sinu iwe-irohin pe kini mo mọ, ṣugbọn nwọn ko ri nkan sọ si mi lara ju wipe mo jẹ ọmọde.

Inu dun wipe ẹgbẹ yi ati ilu nwọn mọ wipe ọjọ ti a ba bimọ lo nde aiye, ọmọ kan ki ida wa si aiye fun ararẹ ẹniti o ba si ti dide; ti o mọ wipe on nfẹ lọ si Igbimọ Nla yi, o ni lati mọ wipe on yio gbọ panpan ọrọ lọkan o jọ okan, bi ota ẹni ba nbu ni ire lo njẹ fun ni, nitori bi enia wọ aṣọ akisa si ọrun, ti nwọn fi bu oluwarẹ, yio tete ran ibiti o ya na.

Mo dupẹ wipe bibu ti nwọn mbu mi, nwọn sọ mi di ọkunrin ni.

Mo mọ iṣẹ nla ti o jẹ lati yan enia si Igbimọ, olukuluku awọn ẹniti o dibo fun mi, o da wọn loju gbangba pe mo nsọro lẹnu, ọro gan ni mo lọ kọ, lati ọdun keje ti mo ti de lati ilu Oyinbo, mo kọ bi, bi enia ti nṣe sọrọ pẹlu lakaye daradara, bi enia ba fẹ sọrọ yio ni ohun ti o nsọrọ le lori, ki o si da nyin loju, wipe lakaye daradara ni emi yio ma lo nibẹ, ki iṣe ki enia kan wulẹ ma sọrọ gburu.

ṣa, emi yio si ma ṣe ẹto ti nba de ibiti ẹ ran mi lọ, ti mo ba ranti pe ilu ti o yan mi o ju awọn ti o wa nibẹ lọ, emi yio ma ba wọn fi ni, nkele leri julọ, iṣẹ ti ẹ fi ran mi, bi mba le jẹ, bi ngo ba si le jẹ, ẹ o ma ri.

Mo dupẹ lọwọ nyin fun diduro ti ẹ duro ti mi nigbati o di wipe k ni yi de gbangba, n torpe mo nwo fẹ ẹ, kilo mu mi ti mo fi nwo fẹ ẹ. Ọgbẹni Benjamin Agba lo je fun mi, ẹwẹ, o si tun je pataki ninu ẹgbẹ yi, on lo si kọ iwe idibo ti a wi yi si olukuluku, mo ri wipe ẹgbẹ yi ki iṣe ẹgbẹ ṣa, nkan ti nwon ṣa ni nwọn yio ṣe nwọn o ṣe bi Ọlọrun fẹ, gegebi ẹ ti fi ọkan tan mi ti ẹ si yan mi si Igbimọ, ẹ ki yio poṣe, mo dupẹ lọwọ nyin.

Emi ni ti nyin ritoto,

KEKERE-AWO.

---

## Olusakin's Column.

---

MR. K. T. MOSETI, B.D. (London).

Mr. Kgalemun T. Moseti, of the Bamangwato people of South Africa, has the distinction of being the first African to become a B.D. (London). *West Africa 22/9/28.* Congratulation.

---

PROMOTION.

Mr. Arthur Ola Derby, 2nd Class Clerk, Marine Department, Lagos, has been promoted to 1st Class Clerk, as from the 11th June, 1928. Heartiest congratulation.

---

DEATH OF MR. T. A. ERINOSHO.

The death is announced on Monday night, the 22nd instant, of the well-known Licensed Auctioneer and Forwarding Agent, Mr. T. A. Erinosho, at Kakawa Street, Lagos—Sympathy.

---

THE RETIREMENT OF MR. J. H. LEIGH.

It is stated on good authority that Mr. J. H. Leigh, 1st Class Compositor, Government Printing Office, Lagos is on 17 days' leave, with effect from the 25th October, 1928, will retire on pension after the expiration of his present leave.

Mr. Leigh joined Service over 30 years ago and rendered a valuable and faithful services.

We wish Mr. Leigh and his wife long life and happiness to enjoy his well earned pension.

## Obituary.

---

ALFA GBADAMOSI DABIRI.

The death took place at his residence, 31, Tairu Street, Lagos, on Friday evening, the 19th October, 1928, of Alfa Gbadamosi Dabiri, a prominent Native Doctor.

The deceased was taken ill for some days, when he was attended by Dr. J. Akilade Caulcrick.

The Late Alfa Dabiri was a very quiet man, kind, popular and unassuming to everybody who came in contact with him.

His remains were removed to the Mohamedan Cemetery at Oke-suna Street, for interment, the following day at 4 p.m., accompanied by many sorrowful friends and relatives.

To his wives Barikisu and Awẹro, to his children Awanatu, Adikatu, Lawani Dabiri, Belo Dabiri and to his twin sister Kẹhinde Dabiri (popularly known as Iya onimọsa) and the rest of the family our sincere condolence. "E ku inawo ile ọmọ a ṣe bẹ fun nyin, ẹhin baba a dara.

---

OPEN LETTERS—PERTINET AND IMPERTINET.

---

To Mr. Henry Theodore Burton,
Lauderdale Mansions, Maida Vale, London.

Sir,—I agree with the Marylebone Magistrate, Mr. Hay Halkett, that you have so far got rid of your wife very cheaply for £127 Very dirtily, too, I think. When you were out of a job, it was agreed you should go home to your mother and your wife should emigrate to Canada to earn her own living, you paying £127 for her passage and outfit. For fifteen months she maintained herself. When ill-health drove her home again, you declined to assist her, although your mother had died and left you £60,000. Probably you will not maintain that callous attitude for long. As the Magistrate reminded you, "the moment your wife makes herself chargeable to the Guardians, a serious position will arise." He means for you.

JOHN BLUNT.

To the Rev. P. Y. Knight,
Ryhope, near Sunderland.

Rev. Sir,—Declaring that silk stockings on artificial legs were a menace to the morals of Ryhope, you are reported to have bought the legs from the local draper who displayed them and to have instructed him to burn them for you. What a naughty mind you must have!

JOHN BLUNT.

13th October, 1928.

OLUṢAKIN.

### ỌKỌ AREFO O.

Awọn Lọya w a korogba-korogba, Ọgbẹni Adeyẹmọ Alakija, Montacute Thompson, S. B. Rhodes wọn ba ọkọ Appam lọ si Port Harcourt Aba, fun ẹjọ Gauran ni ilu wọnyi lẹnu iṣẹ wọn—Ikọ ki kọ ejo lẹsẹ o—ayun bọ ni ọwọ yun ẹnu—Ẹ ma fi oju wa si ọna.

### PA SHAW ỌRUN RE O.

Ni ọjọ *Wednesday* ijọ kẹrinlelogun oṣu yi ni a gbọ iku Baba wa yi to wa ni Alakoro—Asi ba awọn enia Oloku yi kẹdun iku Baba wọn.

### "AṢẸ YI ṢẸ MI"

Aki arakunrin wa John Adophuu Vutade Bright ti 4, Ologun Street ni kọ to wa ni bṣẹ Oyinbo Kessler ni Labinjọ Lane fun ọjọ ibi rẹ ni ijọ *Tuesday* ijọ kẹtalelogun oṣu yi.

### AIYE LU JA ARA WỌN.

Gbangba dẹkun kedere bẹ wo—ọrọ ti mo fẹ lati gbe ẹnu le ninu ọsẹ yi ohun ni n pa ọran òwó lode Eko loni yi nitoripe mo ti pa aṣamọ rẹ bi ọsẹ mẹta sẹhin ṣugbọn ọran dabi ohun ti gbogbo ẹniti ki ṣe Onṣọwo ko mọ riri. Jọwọ mo bẹ nyin ẹnyin Aṣoju wa ni Igbimọ, ki Igbimọ ti ẹ ba wa kẹ ba wa gbe jigi anfani wo ọran wayi. Kini ṣe ti ọja ko ta ni Igboro Eko. Gbogbo enia lo ma wa sọ wipe bi *Cocoa* ba dide ọja yio dide ṣugbọn mo fẹ bere ni ọwọ nyin nję *Cocoa* koi ti so ni ilu Oke ni, tabi wọn koi ti ko sinu apo wa si Eko ni, bere-bere ki ṣi bere ohun lo dila fun won ni ilu Ọbọ wipe kiloṣe ti idi Ọba nyin ṣe pa bayi gbogbo ilu ni ha ha ha, o ni on bere lọwọ nyin ẹ si ni ki on bere nitorina ni on ṣe bere ni ọwọ nyin, nipa bẹ gbogbo nyin lo wa ni ilu ti awọn Oyinbo lọ da ọja si ọja Ejinrin, Ikorodu, Ẹpẹ, Ọlọpẹ, ati Ishara ni Igbo Ijẹbu ẹnyin ko bere wipe nipa bawo gbogbo ohun ti ẹnyin nta fun wọn ni owo geregere wọn nri ni oye kanna, bawo lẹ ṣe nreti wipe ki òwó ko wo ilu—gbogbo *Station* leti Abẹokuta titi de Ibadan ni awọn Oyinbo Onişowo wa, ṣugbọn awọn Aṣoju Oyinbo wọnyi nitori wipe ki wọn le ri Kọmiṣọn ti nwọn, wọn nwọ arọko kiri, nwọn npolowo ọja wọn si nta, ẹnyin ti ẹ wa ni Eko ẹ nreti nwọn wipe wọn fẹrẹ wọ ilu Eko. Ẹ ba ni wo ni ọna miran, wipe awọn Oyinbo wọn ni Aṣoju ni ilu bi Ẹgbẹdi, Ikire, Apomu, Gbọngan, Ashipa titi wọ Ile-Ifẹ gbogbo awọn wonyi ni wọn ni anfani lati bere ohunkohun to ba wun wọnn lọwọ Oyinbo Onişowo won, nwon a si ko wo ilu wọn a si ma ta, iwọ to wa ni Eko wa ma reti wọn wipe awọn ara wọnyi wọn fẹ de si Eko na, ki wọn wa ra ọja. Bo kuro ni Ile-Ifẹ o ni ṣe alai ri Onişowo ni ilu gẹgẹbi *mile* mẹwa si Ile-Ifẹ, bo si de Ilesha titi de Oshogbo to jẹ ogun *mile* wa ri wipe aiye ti lu ja ara wọn titi de ilu bi Akurẹ 73½ *miles* tabi Akurẹ si Ondo 33 *miles* wa ri awọn Onişowo bakanna. Ba mi lọ si ọna Ọwọ de Ifọn lọ si *Benin City* bakanna to ba lọ si *Sapele* wa ni Oyinbo ko si ni Eko. Kiloṣe to fi ri bẹ, mo ni latt sofun nyin wipe bi aiye ti lu ja ara wọn bi a si ti ni anfani Motor lati wọ ilu wọnyi bẹni awa ara Eko ni lati sun ṣokoto wa giri wipe ọja tita ko si ni oju kan mọ aya fi ẹniti o ba ni Aṣoju ni Igbereko kakiri, bo wọ motor lati Agege bẹ ni o ma kan Ṣabu tabi Store awọn Oyinbo Onişowo wọnyi titi la de ilu bi Ifọ tabi Agbẹsi lọ si Papalanto tabi Arigbajo, bo wọ gbogbo arọko wọn yẹn, ko si boju-boju ninu gbogbọ òwó ti nwọn nṣe ni Eko ti ko yẹ wọn, ṣugbọn bi wọn wipe ba mi ra ọja yi bakanna lo ma ba ni Eko, awọn ara Oko wọnyi yio sọfun ẹ wipe, lọ si Ṣabu awọn Miller tabi Alagbọn ni ọdọ wa nibi owo rẹ dinku si ti Eko, ẹnyin enia wa ẹ wa joko si oju kan wipe ọja fẹrẹ dide na, awọn tani o ma gbe dide, tani yio gbe Jakọbu dide ni ọran wa bọsi, nipa bẹ ko si imọran ti a le da si ọran yi ju wipe, ẹnyin enia Dudu papa, ẹ dide ẹ ran enia lọ si ilu Oke tabi arọko wọnyi ki wọ nlọ polowo ọja fun nyin, ẹ ma joko si oju kan, bo ni o ko ṣa joko si oju kan, bẹ ni ọja to ranṣẹ yio joko si Banki tabi Bode ti iwọ yio ma san ele owo si lori, nitori eyiti o gba ni lọlọyi iwọ ti ta tan ko to ni wa ran omiran tabi wa mura lati gba omiran wa si Ṣabu, gbogbo nkan wọnyi nmu ọja joko, o si nmu enia ro wipe emi ti mo ti nta ọja ọgọrun pọnun ni oṣu, kiloṣe ti ngo ko le ta o ni pọnun mẹta, bo ba ro wipe ti Owo-ori ni ko je, ma gbe iyẹn le ọkan daindain, yọ iye owo to ma san ni Owo-ori kuro, elo ni iwọ papa jere na ko to le yọ Owo-ori kuro, gbogbo irohin lo dun lati ma ka sinu iwe irohin, ṣugbọn ẹniti o nfẹ mọ elo lọ wọ ile, ẹniti o ni irinṣẹ tite iwe ko fẹ awin ṣugbọn lode oni l'Eko yi, yala o fẹ ni tabi o ko o ni lati wa wọrọkọ ṣe ada, nitori ki ṣe gbogbo ẹniti o nra iwe irohin lo nfẹ owo lati san, bi iranṣẹ miran jiṣẹ fun ẹniti o jẹ owo iwe, kaka ki *Caraba* na fun ni owo, niṣe ni Tiokomu na ma dahun wipe sọfun Ọga rẹ mi o ni owo ni isẹnyin lati fun bẹni Ọga yi yio san owo fun ẹniti o tẹ iwe fun on nipa bẹ, ai ta ọja ki ṣe wipe ọja ni ko ta ni Eko, ṣugbọn ẹni melo ni o nra ọja ni Eko ode oni, wa ri wipe dię ni, awọn Imale ti nwọn nra aṣọ Iyawo tabi oko, eyi to wa ni ile ni olukuluku nro kakiri, bo ba bere wọn a sọ wipe ko si owo ni ilu, ṣugbọn gbogbo awọn lo ni lọwọ, ki ni iwọ oni Ṣabu Aran ma ṣe pẹlu eyiti oni lọwọ, aya fi bo ba nwo Ọlọrun loju, ẹniti o le pese anfani fun o, nipa tita Aran, Lesi tabi awọn aṣọ meremere to ni lọwọ.

Gbogbo ẹnyin ọkawe wa ẹ ba mi wo, kini ngbe awọn ọkọwe Ṣabu ṣubu loni lode Eko, bi awọn oyinbo ba gba wọn si iṣẹ wọn a sọ wipe iwọ ko gbọdọ ta awin sode, bi iwọ ko ba si fẹ ta wọn a ti ṣabu rẹ, bi iwọ ba si ta awin, nwọn ti ṣabu rẹ, bi ohun ti iwọ ba ta ba busaya, wọn a faẹ le awọn ọpa Ọba ọtẹlẹmuyẹ. lọwọ nipa bẹ awọn awọn

oyinbo won, wọn a fi iwe sode won a wipe awọn nfẹ akọwe si ṣabu awọn to ni iduro, bi enia ko ni iwe ile tabi ko ni owo ṣandi tani ma duro fun nipa bẹ awọn ẹlomiran wọn a ti ma raka wipe ki awọn ri ẹni Ọlọrun kan kimọlẹ ko duro fun awọn pẹlu iwe ile owọ rẹ, awọn enia wa kẹ wọn a ri wipe lagbaja lo wa ni ṣabu awọn oyinbo yi, wọn ani lawọn fẹ ba ṣe owo, wọn a ma ra ọja bi adọta, ọgọrun, adọjọ tabi igba ponwun ti won ba ra tan wọn a da owo silẹ lẹkan awọn akọwe ṣabu wọn a ni awọn ri enia atata, awọn oyinbo to gba wọn si iṣẹ wọn a ni awọn ri ẹniti o dara ju lagbaja lọ, njẹ iwọ sọ fun mi Franki a wa ni ṣabu Miller Sanya a ni on fẹ ra igo whiskey kan, Franki ko ni le ta fun nitori oyinbo mbọ wa ka ọja, sọ fun mi Charlie a wa ni ṣabu Alagbẹn Anthur a ni on nfẹ ra igo Sherry Charlie a ni ko si, tabi Anthony a wa ni ṣabu Mac-Iver Joseph a ni on nfẹ dọsinni milk stouf Anthony a ni ko si bẹni nkan wọn yi, ki ise mimo oju, bi awọn oyinbo ti ngba lọwọ ara wọn niyẹn o di igba ti wọn ba ri aye rẹ ki won to gba owo ni ọwọ ara wọn ko si iyẹn fun enia dudu bi o ṣọti kọbọ kan ilẹkun di titi awọn to nba iwọ jẹ ti wọn nba iwọ nu wọn a si ma yọ ṣuti ete si ọ lọrun so fun nibo ni iwọ wa pẹlu ninu rere rẹ lode Eko loni, iwọ to ti ni ẹṣin ri, iwọ ko ti di ẹniti o nfi ẹsẹ rin lode Eko loni, iwọ gbagbe ara rẹ wipe Eko ki nyago fun ẹlẹṣin eṣi ṣugbọn iwọ nro wipe iye wa ninu rẹ, ṣugbọn pẹlu gbogbo ọgbọn, iye ati mimọ rẹ loni lalai si owo nibo ni iwọ wa, mo ni ran wipe mo kan ninu Eko-akete nigba kan ninu irohin Ile-Ifẹ wipe koral kan ti orukọ rẹ njẹ Zard wa si Ifẹ o si wọ si arin ọja ko le ri ọja ra, ṣugbọn ara Ifẹ wọn kigbe rẹ, o si wa ibomi wọ si, ṣugbọn ki lo mu ti o fi ri bẹ, ko fẹ ki awọn ara Ifẹ ki wọn ra ọja ju on lọ.

*(Koi ti pari.)*

Emi ni ti nyin nitotọ,

ENIA KO DA BI ALLAH.

## TEMI ṢA ! TEMI ṢA ! !

Ko si ohun ti o nmu ilu rẹhin ninu gbogbo nkan ju iwa Temi ṣa ! Tirẹ ṣa !! ti o wa lọwọ awọn ara ilu lọ. Ti a ba ṣe akiyesi ọrọ yi finni-finni, a o ri i pe ohun ti a jo nsowọ po ṣe ju ni ika ( *Wickedness* : ) bi enia meji ba jumọ fi ohun ṣọkan lati ma ṣiṣẹ, tabi owò kan po, ti o ba ṣe si i diẹ bi iwọn ọdun kan tabi meji ti nwọn ti wa lẹnu rẹ, lojiji ni a o gbọ pe nwọn ti ja "aja-tuka bi ti agba-arin."

A ko ni asapẹ fun ohun rere kan bikoṣe ohun buburu ; jẹki ẹnikan ṣeṣi ṣi-itẹ, nipa bibọ sinu pakute Ọba, ki a fẹ ba oluwarẹ rojọ ẹwọn wiwọ, nigbana ni ẹ o ri ainiye awon alayọnusọ, ti nwọn yio joye "bisibeke" alatojubọ ti nwọn yio ma kù sile, kù sode lati tunbọ lẹdi irufẹ ẹni bẹ : nigbayi ni a o ma gbọ oniruru "ma-sọndoki" ọrọ wọnyi, "owọ tẹ ara 'le rẹ wayi. Gale-gale rẹ poju" kini ṣe ? On nikan lo kuku wa nilu ati awọn ọrọ "kobakungbe" miran.

Ohun ti o tun jẹ alebu miran ni pe bi a ba pe ipade kan, iba ṣe nipa ọrọ ilu, tabi ti *Church*, tabi ti ẹgbẹ lasan miran, ti ipade na ko ba gba imọran ti ọkan ninu wọn ba muwa, boya irufẹ imọran bẹ ki yio ṣe Ipade na ni rere kan, ti a si la a ye ẹniti o mu imọran na wa bayi, o di pe ki onimọran na ti a ko ri si imọran rẹ yi di karewa si Ipade na, ki o si ma ibi awọn *member* Ajọ na : Ẹwẹ, boya ọmọde kan lo si mu imọran kan to "tọ suna" ṣugbọn kaka ki awọn agba ipade na gba a nitoripe o dara, agbẹdọ ; ṣiṣa ni nwọn ma ṣa a ti, nitori irufẹ ọrọ iyebiye bẹ ti ọdọ-mọde wa, ti ki nṣe ọdọ wọn ! ni akoko yi ni iwọ yio ma gbọ ọrọ bayi "igberaga ọmọ na rekọja bi Egun kekere to nki baba rẹ ni "Ọku :" "ki o rọra o, la-mọmọ ti nm' egbo ojugun." "Awọn ọgan diẹ to mọ 'we !" Bi a ba wa a lọ, wa a bọ, ẹmi Temi ṣa ! Tirẹ ṣa !! lo mbẹ nibẹ. A ! ọpọlọpọ ohun rібіribi melo la ti paloku larin wa ni ilẹ yi nipa wa yi—iwa anikanjọpọn ?

Gẹgẹbi aiye ti nlọ ti a si ntọ ọ, o yẹ fun ni gidigidi lati mu iru ẹmi bayi kuro larin wa : ki a si ma ṣe afarawe awọn arakunrin ati arabinrin wa, awọn oyinbo, fun iwa iṣokan, irẹpọ ati isọwọpọ ti a nri ngbagbogbo larin wọn fun ohunkohun ti nwọn ba dawọle lati ṣe. A-ki-igbọn-tan.

ADABA.

## EYI ARA !

Ni Satide tokọja ni a tun gbọ pe ina kan tun ṣẹlẹ ni Ereko ni Ṣabu Ọgbẹni kan ti a npe ni Eblene Jazzar, ṣugbọn a gbọ wipe awọn pana-pana bo ina na ki o to di nla nwon pa rẹmu-rẹmu, a gbọ pe ọgọrọ aṣọ ni nwọn ko jade ti ko ṣe bana.—Ẹ kuṣẹ o.

## AWỌN O RI OWO-OLOWO FI ỌKAN BALẸ.

Ni ọsẹ tokọja ni a ri Ọgbẹni kan ni opopo Princes Street, ati ọpọlọpọ enia ti nwọn pe ti i, awa na si duro lati ba ri ifin idi koko, ẹnikan wa sọ fun wa pe ọmọjaguda ni awọn pe ti i, o gbe owo £75 (adọrin pọnwun o le marun) pẹlu ẹgbẹ rẹ, ṣugbọn ngbati awọn ọmọjaguda na ti ko pin owo fun ninu owo na lo ba mu ki on to olowo wa ti o wa bere pe, elo ni Ọgbẹni olowo yio fifun on bi on ba fi awọn ti o gbe owo rẹ han olowo bere pe elo ni iwọ fẹ gba, on dahun pe ogun pọnwun £20 ni on yio gba, tabi, bi o ba le fun on ni £20, ki a ma fa gun lọ titi mọ ibẹ ni ọrọ gbe di ti awọn ọtẹlẹ muyẹ ti nwọn si mu wọn lọ si Tinubu.

TẸNI-MA-SUNWỌN.

## Use Yaro for your baby!

All experienced mothers give testimony in praise of "Yaro" as an indispensable 'Preservative' for 'Babies' Yaro has no equal in suppressing those complaints which make infants feel uneasy, especially during their critical teething period. Trust Yaro for all infants' complaints and use it for your baby. Price per bottle 3/3d & 2/3d.

## Increased health for 3/- only.

"Life Tonic Tablet" imparts tone and vigour to the body, renews every atom of the flesh, prevents brain fatigue and brings indescribable comfort to all mental workers. Price 3/- per bottle.

## A chance for female sufferers.

Wireless Female Pills, the latest Scientific Discovery, have answered divers cases of functional complaints of disorders peculiar to women. These Pills serve as an effective fertiliser against barreness Give "Wireless Female Pills" a trial and prove its reliability.

Our Anti-Plague Disinfectant Fluid kills dangerous flies, bugs. cockroaches, etc., etc. 1/- and 1/6d per bottle.

### Anti-Gon Pills.

Get rid of veneareal diseases before they get rid of you by using Anti-Gon Pills--a reliable antisceptic against Gonorhea. 3/- per bottle.

WE ALSO STOCK:—

Glaxo (large and small sizes)
Vitafer—Brain Tonic
Walk Easy Anti-Rheumatic Salt 3/6 & 2/-
Pile Pills 1/6
Vibrona Wine 7/6
Lactogen
Katzana
Effective Pile Remedy 7/6
Back and Kidney Pills 2/-
Zotal 1/6 & 2/6

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office:*—88, Broad Street, Lagos,
*Branches:*—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
109, Griffith Street, Ebute Metta.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by Victor White, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—Not Obtainable Elsewhere.
"Shake the Bottle."

### AREMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Şugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin şe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loşoşu—Işẹ ti egbogi na nşe ni ara ko şe royin.

Price Ten Shillings (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by Victor White Esq.
41, Offin Road, Lagos.

*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIŞE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati orişirişi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

Price 10/- Per Bottle.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S
## WONDERFUL BRAIN TONIC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, Offin Road, Lagos.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe şişẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy for Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
Victor White, Esq., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price Ten Shillings (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILN ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rẹ mọ (lalai to asiko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Oyi, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.